LASU JOURNAL OF HUMANITIES
(LASUJOH)

VOL. 14, 2020 EDITION | ISSN: 978-274-384-4

A publication of:

Faculty of Arts
Lagos State University, Ojo
Lagos, Nigeria.
Email: dean-arts@lasu.edu.ng

LASU Journal of Humanities
(LASUJOH)

Volume 14, 2020 Edition

© 2020 Faculty of Arts
Lagos State University, Ojo
Lagos, Nigeria

ISSN: 978-274-384-4

Produced by

FREE ENTERPRISE PUBLISHERS LAGOS

HEAD OFFICE: 50 Thomas Salako Street, Ogba,Ikeja, Lagos.
☎+234.814.1211.670.✉free.ent.publishers@gmail.com

FREE ENTERPRISE PUBLISHERS

EDITORIAL BOARD

Editor-in-Chief	Prof. Tayo Ajayi, Dean, Faculty of Arts, Lagos State University, Ojo, Lagos, Nigeria
Editor	Dr. Oseni Taiwo Afisi, Dept. of Philosophy, Lagos State University, Ojo
Associate Editor / Secretary, Editorial Board	Dr. Rasaq Thomas, Dept. of Foreign Languages, Lagos State University, Ojo
Business Manager	Dr. Abayomi Bello, Dept. of Theatre Arts and Music, Lagos State University, Ojo
Managing Editor	Dr. Titilayo Onadipe-Shalom, Dept. of African Languages, Literatures & Communication Arts
Members	Dr. Adewunmi Falode, Dept. of History & Int'l. Studies, Lagos State University, Ojo
	Dr. Adepeju Johnson Bashua, Dept. of Religions & Peace Studies, Lagos State University, Ojo
	Dr. Ayo Ayodele, Dept. of English, Lagos State University, Ojo
	Dr. Maruf Animashaun, Dept. of Foreign Languages, Lagos State University, Ojo
	Dr. Oseni T. Afisi, Dept. of Philosophy, Lagos State University, Ojo
	Dr. Ahmed Adesanya, Dept. of African Languages, Literatures & Communication Arts, Lagos State University, Ojo
	Prof. Sola Fosudo, Dept. of Theater Arts & Music, Lagos State University, Ojo

EDITORIAL CONSULTANTS

Prof. Ihuah Aloysius Shaagee	Benue State University, Makurdi Benue State
Prof. I.S. Aderibigbe	University of Georgia, Athens, Georgia USA
Prof Rauf Adebisi	Ahmadu Bello University, Zaria Kaduna State
Prof. Gbenga Ibileye	Federal University, Lokoja Kogi State
Prof. Bode Omojola	Mount Holyoke College, South Hadley, Massachusetts, USA
Prof. Emmanuel DanDaura	Nasarawa State University, Keffi Nasarawa State
Prof. Antonia Schleicher	Indiana University, Bloomington Indiana, USA
Prof. Toyin Falola	University of Texas at Austin, Texas, USA
Prof. Mashood Baderin	School of Law University of London, Russell Square London, UK

SUBMISSION OF ARTICLES

(Published by the Faculty of Arts, Lagos State University, Ojo, Lagos, Nigeria), the LASU Journal of Humanities encourages submissions from a variety of theoretical standpoints and from different disciplines—especially those that traditionally belong to the all-encompassing "Faculty of Arts" including, however, other areas with which the Faculty has affiliation: anthropology, cultural studies, folklore, media studies, popular culture, communication, sociology and political science.

GUIDELINES FOR AUTHORS

- **Articles**

Authors should submit research articles of (maximum) 10-20 A4 pages, double spaced, 12-point Times New Roman type, in accordance with the MLA or APA style, and include an abstract of not more than 100 words and a "Works Cited" section. Authors should email their articles as Microsoft Word (version 97-2000 or later) format attachment to: dean-arts@lasu.edu.ng

- **Journal Flyer/Call For Paper:**

Every article for publication must be accompanied by a processing fee of Ten Thousand Naira only in cash or by cheque payable to the Faculty Wema Bank Account: LASU FAC Arts Research, Publications & Conference Account Number: 0240791717. Please request a receipt or written acknowledgement for all such payments..

- **Illustrations**

If an article is selected for publication, electronic copies of accompanying illustrations, photographs and diagrams must be provided, as well as all necessary captions. Permission to publish images must be secured by the author. Uncompressed JPEG/PDF file (300 dpi resolution) is the preferred format for all electronic copies. Electronic copies must be sent as e-mail attachments to: dean-arts@lasu.edu.ng

- Warning—Footnotes are absolutely prohibited

  Journal Address: LASU Journal of Humanities
  c/o The Dean, Faculty of Arts, Lagos State University, Ojo
  Lagos, Nigeria. e-mail: lasujournalofhumanities@lasu.edu.ng

- Subscription—The Journal is published twice annually although submissions are accepted throughout the year

Contributors

1. Aande, Simeon Iember
Dept. of Religion & Philosophy,
University of Mkar,
Benue State, Nigeria.

2. Adegbindin, Omotade
Department of Philosophy
University of Ibadan
Ibadan

3. Ajakah, John Chukwuma
Faculty of Humanities, Social &
Mgt. Sciences,
West African Union University
Cotonou, Bénin Republic

4. Apuuivom, Daniel Bem
Dept. of Religion & Philosophy,
University of Mkar,
Gboko, Benue State.

5. Balogun, Badrudeen Adesina
Dept. of Religious Studies
Ekiti State University
Ado Ekiti, Nigeria

6. Bamgbose, Ganiu Abisoye
Dept. of English
Lagos State University
Ojo, Lagos

7. Bamisile, Sunday Adetunji
Dept. of Foreign Languages
Lagos State University
Ojo

8. Bello, Mufutau Olusola
Dept. of Religious Studies
Ekiti State University
Ado Ekiti, Nigeria

9. Fayemi, Ademola Kazeem
Dept. of Philosophy
University of Lagos
Akoka, Lagos

10. Filani, Ibukun
Augustine University
Epe, Lagos, Nigeria

11. Houenon, Casimir
IBB University Lapai
Niger State

12. Hunjo, Henry Jedidiah
Dept. of English
Lagos State University
Lagos, Nigeria

13. Inyaregh, Abel Aor
Dept. of Religious Studies,
National Open University of
Nigeria,
Jabi, Abuja

14. Loko, Olugbenga Olanrewaju
Dept. of Theatre Arts & Music
Lagos State University, Ojo

15. Macaulay-Adeyelure, Olawunmi
Dept. of Philosophy
Lagos State University, Ojo
Nigeria

16. Ndeche, Chinyere C.
Spiritan University
Nneochi, Abia State

17. Ochiai, Takehiko
Professor in African Studies &
International Relations,
Faculty of Law, Ryukoku
University, Japan

18. Olómù, Oyèwolé Ọlamide
Dept. of African Languages,
Literature & Communication Arts
Lagos State University
Ọ̀jọ́

19. Ọ̀nádípẹ̀–Shalom, Títílayọ̀
Dept. of African Languages,
Literatures & Communication
Arts, Lagos State University, Ojo,
Lagos.

20. Onyemelukwe, Ifeoma Mabel
Dept. of French
Ahmadu Bello University, Zaria,
Nigeria

21. Oye, Adetola Olujare
Dept. of Foreign Languages
Lagos State University
Ojo, Lagos.

22. Salman, Hakeem
Dept. of Foreign Languages
Lagos State University,
Ojo, Lagos

23. Taiwo, Adekemi Agnes
Dept. of Linguistics & Nigerian
Languages
Ekiti State University
Ado-Ekiti, Nigeria

24. Umah, Paulinus
Federal University of Lafia
Nasarawa State

Contents

1 "Heaven Helps Only Those Who Help Themselves": Ladipo Solanke and the WASU Hostels in London—Ochiai, Takehiko, ... 1

2 Polygamy and the Rights of Women: Reflections on Religious Feminism —Fayemi, Ademola Kazeem 18

3 Beyond Racism: Language Use, Raciolinguistics and the Cognition of Africa —Adegbindin, Omotade, PhD. 31

4 Referencing and Academic Integrity and Excellence: An Evaluation —Onyemelukwe, Ifeoma Mabel 42

5 A Constructivist Critique of Gene Editing—Macaulay-Adeyelure, Olawunmi 53

6 Referring Expressions in Nigerian Stand-Up Contexts—Filani, Ibukun & Bamgbose, Ganiu Abisoye 63

7 José Luandino Vieira: Marcas de Africanidade, Inovação E Autenticidade No Texto Literário—Bamisile, Sunday Adetunji, PhD 83

8 Analysis of *Gangbe* Music of Badagry Ogu Community, Lagos, Nigeria —Loko, Olugbenga Olanrewaju, PhD 95

9 The Fanti Carnival in Lagos and its Message of Morality—Ọ̀nádípẹ̀-Shalom, Títílayọ̀. . . . 106

10 The Life and Times of Musa Ajagbemokeferi: 1933-2000—Bello, Mufutau Olusola, PhD & Balogun, Badrudeen Adesina. 113

11 Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Èro Yorùbá Nínú Orin Fuji Saheed Ọ̀ṣùpá—Taiwo, Adekemi Agnes 125

12 A Study of Lexical Priming in Newton Jibunoh's *Hunger for Power* —Hunjo, Henry J., PhD & Ajakah, John Chukwuma 137

13 Fífi àṣà Ìṣèlú tìpá Tìkúùkù yiiri Ìpolongo Ìbo ni Ipilẹ̀ Èkó—Olómù, Oyèwolé Ọlamide 156

14 L'Implication de la Theorie du Skopos dans la Traduction des Anthroponymes —Oye, Adetola Olujare, PhD. 168

15 Traduire le hanló ou la chanson satirique fon en français: Dilemme identitaire, défis et fonctionnalité—Houenon, Casimir & Umah, Paulinus 177

16 Conversational implicature and Politics in Achebe's *A Man of the People* —Ndeche, Chinyere, PhD. 191

17 Nehemiah's Strategy of Fighting Corruption and Injustice in Neh. 5: 1-19: Implication for Incorruptible and Just Leadership in Nigeria's Democracy—Apuuivom, Daniel B., PhD, Inyaregh, Abel A., PhD & Aande, Simeon I., PhD 202

18 Salman, Hakeem, PhD— الموشّحات الأندلسيّة : ثورة فنّيّة اجتماعيّة علي الشعر العربي الكلاسيكي 214

11

Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Èro Yorùbá Nínú Orin Fuji Saheed Ọ̀ṣùpá

Taiwo, Adekemi Agnes

Àsamọ̀

Onírúurú orin ló wà ní àwùjọ Yorùbá lóde òní. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀ nínú àwọn orin wọ̀nyí ni ó ní ipa búburú lórí àṣà, èdè àti iṣe Yorùbá, síbẹ̀ a kò ṣàìrí àwọn olórin àsìkò yìí tí ìgbéláruge àṣà Yorùbá sì jẹ lógún. Àwọn onímọ̀ ti ṣiṣẹ́ lórí orin fújì àmọ́ wọn kò tíì mẹ́nuba ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá lórí rẹ̀. Fún ìdí èyí, iṣẹ́ yìí se àgbéyẹ̀wò orin fújì Saheed Ọ̀ṣùpa , gẹ́gẹ́ bí ó se ṣàfihàn àṣà àti iṣe Yorùbá.. Iṣẹ́ yìí ló fẹ́ ṣe afihàn ọ̀kanọ̀jọ̀kan ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá tí ó hànde nínú àwọn àṣàyàn orin fújì tí Ọ̀ṣùpá kọ.Àwọn ìwà ọmọlúàbí àti àṣà Yorùbá ni ọ̀kọrin gbé láruge nínú àwọn àwo orin yìí. Tíọ́rì ìfojú àṣà ìbílẹ̀ wo iṣẹ́ ọ̀na aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ ni a ṣàmúlò láti se ìtúpalẹ̀ àwọn àyọlò orin náà ní bí tíọ́rì náà ti fikún ìmọ̀ wa nípa orin fújì àti bí orin ọ̀hun ti ń táyése nípa ṣíṣe àfihàn àṣà àti ìgbàgbọ̀ Yorùbá. Ìrètí wa ni pé iṣẹ́ yìí yóò ta wá jí láti máa ṣàgbéláruge àwọn àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá tó ti forí mù lójúnà à ti mú àwùjọ wa dára si

Kókó Ọ̀rọ̀: *Orin fújì, àṣà àti ìgbàgbọ́ Yorùbá, ìwà ọmọlúàbí, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá.*

Ìfáárà

Orín jẹ́ ìsọ̀rí ẹ̀yà ewì alohùn Yorùbá (Ọlátúnjí ,1984). Kò sí ìgbà tàbí àkókò tí ènìyàn kò le kọrin àmọ́ àwọn Yorùbá a máa kọrin ní ìbámu pẹ̀lú ìgbà, àkókò, ìrírí àti àfojúsùn wọn. Láti ayé bá ayé ni àwọn baba ńlá Yorùbá ti máa ń kọrin. Orin jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí ènìyàn fi máa ń gbé èrò ọkàn rẹ̀ jáde, ohun tí ó múmú láyà ọ̀kọrin ló máa ń gbé jáde. Ọ̀kọrin le fi orin mú ìwúrí àti ìdùnnú bá ara rẹ̀ àti ẹlòmíràn. Gẹ́gẹ́ bí alóre àwùjọ, ọ̀kọrin lè fi orin gbé ẹ̀dùn ọkàn àwọn ará àwùjọ jáde. Orin lè mú ènìyàn sa ipá láti ṣe ohun tí ó dàbi pé ó ṣòro nígbà mìíràn. Àwọn Yorùbá fẹ́ràn orin, kò sí ẹ̀ka ìgbé ayé wọn kan tí orin kì tí i jẹ jáde; yálà nínú ayọ̀ tàbí ìbánújẹ́, lákòkóò ìpàdé tàbí ìgbà lílò, lákòkóò ìgbaniníyànjú tàbí ìbániwí, gbogbo èyí ni orin wà fún láti fi gbé èrò ọkàn ẹni jáde.Olukoju (1987:8) fidí èyí múlẹ̀ nígbà tí ó sọ pé “orin ni a fi ń gbé èrò ọkàn wa síta fún aráyé, bóyá nínú ayọ̀ tàbí nínú ìbànújẹ́, ní ìyìn tàbí

ìdúpẹ́." Orin jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀yà ewì alohùn Yorùbá, gbogbo ẹ̀ka ìgbé ayé ọmọ Yorùbá ni orin ti ń jẹ jáde.

Scholes (1952: 540) sọ pé "Song is a natural means of self-expression." Orin jẹ́ nǹkan àbímọ́ tí a fi ń gbé èrò ọkàn ẹni jáde. Èyí túmọ̀ sí pé orin jẹ nǹkan tó wà nínú ẹ̀jẹ̀ wa, tí a sì ń lò ohùn wa láti fi gbé èrò ọkàn wa síta. Ulli Beier (1956:23) nínú Ọlátúnjí (1984:8) sọ pe ìran Yorùbá fẹ́ràn orin débi pé gbogbo ayẹyẹ tí wọ́n bá ń ṣe ni orin ti máa ń jẹ jáde. Kò sí ohun tí àwọn Yorùbá kì í fi orin ṣe nítorí náà; orin jẹ́ ohun ìní àwùjọ Yorùbá.Ó jẹ́ ohun èlò ìtura, ìdùnnú, àtúnṣe àti ìmúdúró àwùjọ Yorùbá.Oríṣiríṣi ẹ̀yà orin ló sì wà láwùjọ Yorùbá bíi orin ìdárayá, ìtùnú, orin arò, orin ìyìn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bákan náà ni a tún ní àwọn orin bí orin ifá, orin ìjálá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Sunday (2011) ni tirẹ ni orin jẹ́ irinsẹ́ tí a fi ń gbé àṣà àti ìwà ọmọlúàbí lárugẹ láwùjọ Yorùbá. Lóòótọ́, oríṣìíriṣí ẹ̀yà orin ló wà láwùjọ Yorùbá, àmọ́ orin Fújì tí Saheed Ọ̀ṣùpá ni ó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ yìí.

Orin Fújì Ní Àwùjọ Yorùbá

Lára orin wéré èyí tí wọ́n máa ń kọ lákòkò ààwẹ̀ àwọn Mùsùlùmí ni orin fújì ti jẹ jáde. Adégbìtẹ́ (1989:35) se àgbéyẹ̀wò orin fújì, wéré àti àpàlà. Ó ní láàárín àwọn Yorùbá ni orin fújì ti dìde. Ó tẹ̀síwájú pé :

> Traditional fuji was believed to first emerge among the Yoruba as an adaptation of" wéré" islamised musical genre in the 70s but technically, it resembles Àpàlà; another islamised musical genre.
>
> Láti ara orin wéré èyí tí í se orin àwọn ẹlẹ́sìn ísíláámùni a gbàgbọ́ pé orin fújì ti kọ́kọ́ jáde ní bí i ọdún mẹ́tadínláàdọ́ta sẹ́yìn, léyìí tí ó sì jẹ́ pé láti ara orin àpàlà tí í se orin àwọn mùsùlùmí bákan náà ni òun náà ti jẹ jáde.

Adégbìtẹ́ sọ pé orin wéré yìi ló bí gbogbo àwọn orin fújì ìgbàlódé òde òní. Òhun ni àwọn ẹlẹ́sìn Mùsùlùmí ń lò láti jí àwọn ẹlẹgbẹ́ wọn lásìkò ààwẹ̀. Orin fújì jẹ́ gbajúgbajà lára àwọn ọ̀kanọ̀jọ̀kan orin tó wà ní órílẹ̀-èdè Nàíjíríà.Àlájì Síkírù Àyìndé Barrister ló sọ orin wéré di ìlúmọ̀ọ́ká.Àlájì Dáúdà epo Àkàrà tó jẹ́ olùdásílẹ̀ orin Àwúrèbe ló sọ orin yìí di gbajúgbajà. Lára àwọn tó kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ sí ní kọ orin ajíwéré yìí ní ìsàlẹ̀ Èkó ni Jíbówú ni Àlájì̀ Síkírù Àyìndé Barrister ẹni tí Saheed Ọ̀ṣùpá kọ́ṣẹ lọ́wọ́ rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí olùdásílẹ̀ orin Fújì ti sọ, orúkọ yìí "fújì" ni ó yàn fún orin yìí nígbà tí ó rí ìwé ìpolówó ọjà kan tí wọ́n fi ń kéde orí òkè fújì ní pápákọ̀ òfurufú, orí òkè yìí ló sì ga jù nílẹ̀ Japan. Àlájì Síkírù Àyìndé Barrister sọ pé nínú orin fújì ni a ti le rí Sákárà, Àpàlà, Jùjú, Afro, gúdúgúdú àti Highlife, (Wikipedia). Òun ló sì gbé orin yìí káàkiri àgbáyé tó jẹ́ kó di gbajúgbajà nílẹ̀ aláwọ̀ funfun. Láàárín ọdún 1970 sí ọdún 1980 ni àwọn olórin Fújì mìíràn dìde tí àwọn náà sì ń kọ irú ẹ̀ya orin Fújì wọn. Àwọn bíi Fàtáì Àdìó Súàrá, Àlájì Kollington Ayinla, Ìyàndá Sàwábà, Wàsíù Àyìndé Barrister tó wá padà di (Wàsíù Àyìndé Marshall), Rasheed Àyìndé àti Sùláímọ̀n Àdìgún.

Kín ni Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Èrò Yorùbá?

Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò ló ń kópa ribiribi nínú ètò ìgbé ayé ọmọnìyàn láwùjọ nípa síṣe

ìgbéjinlẹ̀ àti ìtọpinpin ohun gbogbo tó jẹ mọ́ àṣà, ìṣe àti ìgbàgbọ́ wọn léte àti mú ìtẹ̀síwájú dé bá àwùjọ ọmọnìyàn. Ọ̀pọ̀ nínù àwọn onímọ̀ ló ti siṣẹ́ lórí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá, Ògúnṣínà (2006), Ògúnṣínà (2009) Ọládípọ̀ (2007) àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ fìdi rẹ̀ múlẹ̀ nínú àpilẹ̀kọ wọn pé Yorùbá ní ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò. Ọládípọ̀ (2007) ṣàlàyé pé:

> The term "Yorùbá philosophy" in this context should be understood to mean not simply a body of ideas, collective and individual in term of which the world and the twist and turns of human experience are explained, but also a system of values and attitude which guides lifestyles and conduct. This Yorùbá Philosophy not only includes the ideas of the Yorùbá on life, existence, reason, knowledge and so on, as embodied in the language and oral traditions of the people, and as exhibited in their social practice.
>
> Ohun tí à ń pè ní ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá nínú àyọlò yìí kò dúró lórí èròngbà àwọn ènìyàn yálà ẹnìkọ̀ọ̀kan tàbí àgbájọpọ̀ ènìyàn láti ṣe àlàyé ìrírí ayé wọn, ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí ohun àmúyangàn àti ìwà ọmọlúàbí tí ó ń ṣe àtọ́kùn fún bí a ti ń gbé ìgbé ayé wa. Nípasẹ̀ èyí, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá kọjá èròngbà Yorùbá nípa ìgbé ayé, ìwàláàyè, èrèdí, ìmọ̀ àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ bí ó ṣe jẹyọ nínú èdè, lítíréṣọ̀ wọn àti bí ó ṣe jẹyọ nínú àṣà ìbára ẹni gbépọ̀ wọn.

Ohun tí àyọlò yìí ń tẹnumọ́ ni pé, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá wà pẹ̀lú ẹnì kọ̀ọ̀kan àti ọmọ Yorùbá lápapọ̀ bí ó ti ń jẹyọ nínú ìrònú, ọ̀rọ̀ àti ìṣe wọn. Ó sọ pé a le rí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èro nínú àṣà ìbára-ẹni-gbépọ̀, èdè, lítíréṣọ̀ àti onírúurú ìrírí, àyíká àti àyídà ilé ayé. Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò yìí ni Dáramọ́lá àti Jẹjẹ (1975) pè ní èrò àwọn Yorùbá nípa àwọn nǹkan tí wọn gbàgbọ́. Èyi jẹyọ nínú ìgbàgbọ́ wọn nípa Olódùmarè, àṣà àti ìṣe Yorùbá ní gbogbo ọ̀nà. Ògúnṣínà (2006: 106) ṣe àpéjúwe ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò pé:

> ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èro ni ẹ̀kọ́ tó ń ṣe àyẹ̀wò fínnífínní àti àwòjinlẹ̀ ìtumọ̀, èrèdí àwọn nǹkan tó ṣe pàtàkì nínú ìrònú, ìgbàgbọ́ àti íṣe ọmọnìyàn

Àwọn atúmọ̀ lórí ìtàkùn àgbáyé sọ oríkì ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò báyìí:

> Philosophy is the discipline concerned with the questions of how one should live, what sorts of things exist and what are their essentials to nature
>
> Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èro ni ẹ̀ka ẹ̀kọ́ tí ó ń ṣe àwárí ìmọ̀ nípa bí a ṣe gbọ́dọ̀ gbe ìgbé ayé wa, àwọn nǹkan tí ó wà nínú ayé àti pàtàki wọn

Èyí ló ń ṣàfihàn èrèdí ìwàláyé níbi ìmọ̀ yìí ti ǹ ṣe ìtọpinpin, ìwúlò àwàjinlẹ̀ àti pàtàkì onírúurú nǹkan tó rọ̀ mọ́ ìgbésí ayé ọmọ ènìyàn. Pépà yìí ṣàgbéyẹ̀wò oríṣìíríṣí ipa tí orin Saheed Ọ̀ṣùpá ti ní láwùjọ nípa ṣíṣàmúlò ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùba láti gbé àṣà làrugẹ.

Tíọ́rì Ìfojú Àṣà Ìbílẹ̀-wo Lítíréṣọ̀

Ohun tí àwọn agbátẹrù tíọ́rì tẹpẹlẹ́ mọ́ ni kókó iṣẹ́ tí iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ ń se, nítorí náà ohun tí ó gbọ́dọ̀ jẹ lámèètọ́ lógún ni ṣíṣe àfihàn irú àwọn àṣà tó ṣúyọ nínú iṣẹ́ rẹ̀. Àwọn tó sẹ̀dá tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wo àwùjọ se èkúnrẹ́rẹ́ àlàyé pé ojúlówó iṣẹ́ lítíréṣọ̀ láwùjọ ẹ̀dá ni láti dáàbò bo àṣà àwùjọ (Adeyemi, 2006:25).

Òǹkọ̀wé gbọ́dọ̀ ṣàwárí àwọn àṣà tó ti forí mù kí wọ́n sì se àfihàn wọn lọ́nà tí yóò fi gbé àṣà adúláwọ̀ láruge. Ọ̀nà méjì ni àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí pín sí; àwọn ìsọ̀wọ́ kìínní rí àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun tí kò gbọdọ̀ yípadà, bí wọ́n se bá a náà ló gbọ́dọ̀ máa rí lọ. Àwọn ìsọ̀wọ́ kejì ni àwọn tó gba àṣà ní atáyése. Àṣà tó se é tẹ̀lé, tó sì le è tanijí ni wọ́n gbé láruge. Irú àwọn àṣà bá wọ̀nyìí ni a ó máa ṣàgbéyẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí.(Fanon 1967, ati Ngugi wa Thiongo ninu Adeyemi, 2006) Àwọn ọ̀kanọ̀jọ̀kan àṣà atáyése tó ti forí́mù tí a ṣàwárí nínú orin Òṣùpá ni a ṣàgbéyẹ̀wò ní ìibámu pẹ̀lú ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá. Lójúnà àti ṣàlàyé lẹ́kùnrẹ́rẹ́ lórí àwọn orin Saheed Òṣùpa, a ṣàmúlò àwọn àwo orin rẹ̀ máàrún. A sì se àyẹ̀wò àwọn ìwé tó yẹ láti se ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí.

Ta ni Saheed Òṣùpá?

Ọdún 1969 ni a bi Saheed Àyìndé Babátúndé Akóredé Okùnọlá. O jẹ́ ọmọ bíbí ìlú Ìbàdàn ní agboolé Láníba, Ayẹ́yẹ́. Ó bẹ̀rẹ̀ ilé ìwé alákọ́bẹ̀rẹ̀ ní Saint Mary's Primary School, Ajégúnlẹ̀ ní ìlú Èkó ní ọdùn (1975-1981). Amúwo Ọ̀dọ̀fin High School, Mile 2 (1981-1986) ní Èkó. Ó tẹ̀síwájú lọ sí ilé-ìwé gbogbonìṣe ti ìlú Ìbàdàn níbi tó ti kẹ́kọ̀ọ́ gboyè OND nípa ẹ̀kọ́ṣẹ́ ìsàkóso okòwò (Business Administration). Ó tún tẹ̀síwájú lọ kẹ́kọ̀ọ́ lókè òkun lórí ìmọ̀ nípa ẹ̀rọ ayárabíàṣá ní American International College. Àjogúnbá ni iṣẹ́ orin fún òǹkọrin yìí, ó tún jẹ́ iṣẹ́ tí ó fẹ́ràn jùlọ láti ṣe, èyí ló mú kí ó yarantí lááàrin àwọn òǹkọrin fújì ẹlẹgbẹ́ẹ̀ rẹ̀.

Ọ̀dun 1983 ni ó bẹ̀rẹ̀ orin kíkọ gẹ́gẹ́ bi ọ̀dọ́. Ìràwọ̀ rẹ̀ tàn nígbà tí ó gbé àwo orin àkọ́kọ́ rẹ̀ tó pè ní Fújì Disco jádè.Ó sì ti gbé àwo orin méjìdínlọ́gbọ̀n jáde. Lára wọn ni "Fújí Blues," "Fújí Demostration," "Stainless," "Master Blaster," "Respect," "London Delight," "Barrybration," "Transparency" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọdụn 2008 niÀlájì Àyìndé Barrister gbé adé lé lórí bí ọba orin fújì. Saheed Òṣùpá ló tún máa ń kópa nínú àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá.Ó ti kópa nínù ọgbọ̀n fíìmù.Ó sì ti gba àmì ẹ̀yẹ lórí orin fújì àti fíìmù. Orúkọ tí gbogbo ayé mọ̀ ọ́n sí biakọrin fújì ni Saheed Òṣùpá. (kingsaheedosupa blogspot.com/……/king Musicography)

Àtúpalẹ̀Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Èrò Yorùbá Nínú Orin Fújì Saheed Òṣùpá

Ọkanọ̀jọ̀kan iṣẹ́ ìwádìí ló ti wáyé lórí orin ìbílẹ̀ Yorùbá.Àwọn onímọ̀ ti sọ̀rọ̀ lórí orin àpàlà, orin dadakúàdà, orin wákà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn míran tilẹ̀ ti ṣiṣẹ́ lóri orin fújì àmọ́ wọn kò tíì mẹ́nuba ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá lórí rẹ̀ àyàfi tí oríkì àwọn ìlú kan pẹ̀lú orin ajẹmẹ́sìn. Oríṣiriṣíi àṣà Yorùbá tó ń ṣàfihàn ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò wọn ni Saheed Òṣùpá máa ń kọ jáde nínú orin fújì rẹ. Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá nípa ikú, ìwà ọmọlúàbí, ìbáraẹnigbépọ̀, ọmọ, ìfẹ́ àti ìgbéyàwó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni a ó máa ṣàgbéyẹ̀wò rẹ̀ nínú orin Saheed Òṣùpá.

Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Èrò Yorùbá Nípa Ọmọ àti Ìwà Ọmọlúàbí

Ẹ̀yà Yorùbá jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀yà tó ka ọ̀rọ̀ ọmọ kún èyí tí í se ẹ̀bùn kan tó se pàtàkì jùlọ nínú ẹ̀bùn tí Ọlọ́run máa ń fún ẹ̀dá. (Ladele aty 1986:137) Nítorí èyí ni ìran Yorùbá fi máa ń ki ọmọ pé:

Ọmọ,ọmọ-ọ̀sìn
Ọmọ tíí bo ni lára bíi aṣọ

Ọmọ niyì, ọmọ laṣọ

Níjọ́ a bá kú, ọmọ làdèlé

Ọmọ ẹni ni tẹni

. . . .

Bọ́gẹ̀dẹ̀ bá kụ́, á fọmọ ẹ̀ rọ́pọ̀ (Ladele aty 1986:138)

Àwọn Yorùbá a máa kọ́ ọmọ wọn ní ìwà ọmọlúàbí bíi: bi a ti ń jókòó, jẹun àti bí a ti ń kí àgbàlagbà lówùrọ̀ bí a bá jí pẹ̀lú ọ̀kanọ̀jọ̀kan ìwà tí yóò jẹ́ kí wọ́n mọ̀ pé ilé rere ni ọmọ náà ti jáde wá. Ọ̀ṣùpá nínú orin rẹ̀ “Like father Like son” jẹ́ kí á mọ pàtàkì ìwà ọmọlúàbí (ìgbọ́ran) nínú ayé àwọn ọ̀dọ́mọdé. Ó ní:

Ìwọ̀ ọ́mọ mì yé

Ìwọ̀ ọ́mọ mì a

Ìwọ̀ ọmọ mì i, dákun gbọ́ tèmi,

Gbogbo nǹkan tí mo bá ẹ sọ

Má ṣàì gbọ́nran, dákun gbọ́ tèmi

Àrán ni o dá, ọmọ mi má dáràn

Àrán ni o dá o, ọmọ mi má dáràn

Torọ́mọ tó dáràn, á sọ baba lẹ́nu

Torọ́mọ tó daràn, á sọ yeye lẹ́nu

Á sọ ẹbí lórúkọ, ọmọ mi má dáràn, ko má somí lórúkọ

Èyí fihàn pé Yorùbá nígbàgbọ́ nínú ìwà ọmọlúàbí nítorí ọmọ tó bá hùwà ọ̀danràn níí fi ọwọ́ òsì júwe ilé baba rẹ̀.Yóò sì tún ba orúkọ ẹbí jẹ́ pátápátá gẹ́gẹ́ bí ọ̀kọrin ti sọ. Olórin tún tẹ̀síwájú nínú àròjinlẹ̀ rẹ̀ lórí pàtàkì ọmọ nígbà tó sọ pé:

Àrán ni o dá

Bójú bá rí ọmọ Gbọ́láhàn ọmọ mi Hàbíbù yìí;

íbí tí mo bi ayé ẹ má fa fọ́tò yìí ya

èsù má fa fọ́tò yìí ya

Mo ní à fi késù má fa fọ́to yìí ya

Àwọn Yorùbá ló máa ń ka ọmọ sí gíláásì tí a fi ń ríran àti fọ́tò.Ọ̀ṣùpá gba àwọn ọmọdé níyànjú láti má dáràn àmọ́ kí wọ́n dá aṣọ àrán. Aṣọ àrán jẹ́ aṣọ iyì, olówó iyebíye tí àwọn Yorùbá kà sí aṣọ ẹ̀yẹ nítorí náà ni òkọrin fi ń pàrọwà sí àwọn ọmọ láti má dá ọ̀ràn pẹ̀lú àdúrà pé kí ọtá má pawá lọ́mọ. Ìdí tí Yorùbá fi máa ń bímọ tún jẹ jáde nínú àyọlò yìí nítorí pé “bíná bá kú á feérú bojú, bọ́gẹ̀dẹ̀ kú á fọmọ rẹ̀ rọ́pò.” Ọmọ ẹni ni yóò gbẹ̀yìn tẹ́yìn se lẹ́yìnwá ọ̀la. Ìwà ọmọlúàbí ọmọ ni yóò sì jẹ́ kí irú ọmọ bẹ́ẹ̀ lè tẹ́yìn se.

Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ìwà ọmọlúàbí” ni àṣà ìbọ̀wọ̀fúnni, ìṣiṣẹ́kára àti ìwàpẹ̀lẹ́ sodo sí. Gbogbo ìwà adámọ́ ẹni tí ó ní ìwàpẹ̀lẹ́ èyí tí í se baba ìwà ni ọ̀rọ̀ sísọ. Àwọn Yorùbá a máa fẹ́ràn kí ènìyàn ní ọpọlọ pípé kó sì mọ ọ̀rọ̀ sọ.Ìtẹ́ríba tàbí ìbọ̀wọ̀fúnni tún jẹ Yorùbá lógún púpọ̀, bákannáà ni òtítọ́, ìwà rere, akínkanjú, iṣẹ́ àti ọpọlọ pípé. Gbogbo àwọn ìwà ọmọlúàbí ni kò ní ohun kan se pẹ̀lú ẹ̀sìn bíkòse ìwà ẹ̀dá. Idowu (1962) ninu Ogundeji ati Akangbe (2009:34) ṣàlàkalẹ̀ àwọn ìwà tó yẹ kí ẹni

ti à ń pè ní ọmọlúàbí gbọ́dọ̀ ní. Lára wọn ni: ìtẹ́lọ́rùn, ìmáradúró saájú ìgbéyàwó, ìgbàlejo, ìṣoore, ikááánú, ìjóólòótọ́, ìbọ̀wọ̀ fún òbí, àwọn tó junilọ àti àwọn tó wà nípò àṣẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọkọrin ló sọ̀rọ̀ nípa àṣa ìbọ̀wọ̀fúnni nígbà tí ó ń gba àwọn ọmọdé níyànjú láti máa bọ̀wọ̀ fún àgbà.

Ọmọdé ẹ máa fàgbà, arúgbó tayín

Ẹ yé máa fàgbà kọ́rọ̀ sọ

Kágbà náà máà fàgbà rẹ́ ọmọdé jẹ mọ́

Torí pé ibi tágbà bá sì wà lọmọdé máa bá a

Yorùbá ló ní ìgbàgbọ́ pé ìwọ̀tunwọ̀nsì lọ̀rọ̀ ilé ayé.Ọmọdé gbọ́n, àgbà gbọ́n la sì fi dá ilẹ̀ ifẹ̀. Bẹ́ẹ̀ ló sì tún ní bọ́mọdé bá ti ń bọ̀wọ̀ fún àgbà, kí àgbà náà fi ara rẹ̀ sí ipò ọ̀wọ̀, kí ó máse fi àgbà rẹ́ ọmọdé jẹ.

Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá nípa ìwà ọmọlúàbí tí Ọ̀ṣùpá ṣàfihàn ló fi ń bá àwọn òbí wí pàápàá jùlọ àwọn baálé ilé tí kò bìkítà láti ṣe ojúṣe wọn. Baálé tó bá jẹ́ ọmọlúàbí yóò máa se ojúse rẹ̀ nínú ilé àti láàárín ẹbí. Orin náà lọ báyìí:

Tẹ́ti kó o gbọ́, ọkọ ìyàwó

O fọmọ sílé, o faya sílé

Tẹbí tará, wọ́n ń bẹ níbẹ̀

O ò tọ́jú wọn, gbogbo owó tóo ní

O fi ń se fàájì kiri

Kíni kátikàti?

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní "òwú ìyá gbọ̀n lọmọ ń ran'; nígbà tí ẹni tí a pè ní baálé ilé bá ń hùwà pálapàla, irú kí ló fẹ́ fi le ọmọ lọ́wọ́.Ọjọ́ ọ̀la irú bàbá tàbí baálé báyìí ló fi ń seré, torí kò ní fi àpẹẹrẹ rere tí ó rọ̀ mọ́ ìwà ọmọlúàbí lélẹ̀fún àwọn ọmọ rẹ̀. Adágbádá (2014) ni ọmọlúàbí ni ẹni tó se é fọkàn tán, tí ó si se é gbẹ́kẹ̀lé nígbà gbogbo. Ìwà ọmọlúàbí tí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá ń ṣàfihan tún jẹyọ nínú orin "The Main Man" pẹ̀lú àkọ́lé tó pè ní " Good Deed'(ìwà rere). Ọ̀ṣùpá fi orin yìí gba àwọn ọmọ ẹ̀dá níyànjú láti máa se rere nítorí pé a ó jèrè ohun gbogbo tí a bá se lọ́jọ́ kan. Ìtàn kan ló fi se àpèjúwe ìwà rere nínú orin yìí:

Bó o serere àbọ̀wábá

Bó ò serere, wà á ba níbẹ̀

Àtoore àtìkà á gbẹ̀san

Ẹní dájọ ló ń kájọ

Ẹní dájọ ló ń kájọ

Ẹní dájọ ló ń kájọ

Èèyàn ò lè gbinlá, kó húùfọ́

Ló mú mi rántí ìtàn kan

Ẹnì kan wà tó se pé ó ń bẹ nílùú òyìnbó

Ó ṣiṣẹ́ kárakára, ó ń fowó ránṣẹ́ sílé

Ẹgbọ́n ẹ̀ ló ń bá a kọ́lé
Bó o sérere, àbọ̀wábá
Bó ò sérere, wà á ba níbẹ̀

Ìtàn yìí ni Ọ̀ṣùpá fi kọ́ni ní ìwà rere èyí tí Yorùbá gbàgbọ́ pé òun ni ẹ̀ṣọ́ ènìyàn. Ẹ̀gbọ́n yìí ló kọ́ ilé ẹgẹrẹmìtì de àbúrò, àmọ́ nígbà tí àbúrò dé látòkè òkun, owó ti pọ̀ si. Ó sì lọ ra ilé ńlá.Ó wá fún ẹ̀gbọ́n ní ilé tí ó bá a kọ́.Kò pẹ́, kò jìnnà tí ẹ̀gbọ́n kó dénú ilé, lòjò rọ̀, tó wó ilé náà. Ìtàn yìí ni ọ̀kọrin fi kọ́ wa pé ẹ̀san wà fún ohun gbogbo, tó bá jẹ́ pé ẹ̀gbọ́n kò kówó àbúrò rẹ̀ ná, kó kọ́ ilé tó dára, bí ilé ọ̀hun kì bá ti jẹ́ tirẹ̀ náà nìyẹn.

Ìwà ọmọlúàbí míràn tí Ọ̀ṣùpá tún ṣàfihàn nínú orin rẹ̀ ni ìjóólòótọ́. Ó jẹ́ kí àwọn olùgbọ́ rẹ̀ mọ̀ pé ìjóólòótọ́ se pàtàkì láàárín ọ̀rẹ́ sí ọ̀rẹ́, ọ̀gá sí ọmọ iṣẹ́, ọkọ àti ìyàwó.Ó ní kò si bí ènìyàn ti jóólòótọ́ tó tí kò ní jèrè ìwà rẹ̀ lẹ́yìn-ò-rẹyìn. Irọ́ pípa kò lẹrè.

Òtítọ́ lẹ́mìí gígùn gan, kò dà bí i irọ́
Ìtìjú mà ló ń gbẹ̀yìn rẹ̀, bírọ́ bá já
Kí ló lérè tó òtítọ́ láyé
Olórí lo jẹ́ níbì kan, fòtítọ́ se
Ìtìjú mà ló ń gbẹ̀yìn rẹ̀ bírọ́ bá já
Kí ló lérè tó dàbí òtítọ́ láyé
Ọmọsẹ́ lo jẹ́ níbì kan, fòtítọ́ ṣiṣẹ́
Ìtìjú mà ló ń gbẹ̀yìn rẹ̀ bírọ́ bá já
Kí ló lérè tó dàbí òtítọ́ láyé
Ọkọ sí ìyàwó rẹ̀ gan, fòtítọ́ bá a gbé

Ọ̀ṣupà ló ka písọ òtítọ́ sí ara ìwà ọmọlúàbí pẹ̀lú àrọwà pé ẹ̀yìn olóòótọ́ ni Ọlọ́run ọba máa ń wà nígbà tí ó ń parí orin náà.

Ṣọmọlúàbí kó o sòtítọ́
Ẹ̀yìn olóòtítọ́ l'Ọlọ́run má ń wà
Sòtítọ́ o, ká le gbèjà rẹ ja.

Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Èrò Yorùbá Nípa Orí Àti Àyànmọ́

Nínú ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá, orí tí wọ́n tún máa ń pè ní àyànmọ́ ni wọ́n gbàgbọ́ pé ó wà nínú agbárí nítòsí ọpọlọ èyí tí wọ́n tún máa ń pè ní òrìsà ẹni, olùtọ́sọ́nà ènìyàn, ẹlẹ́dàá, òun kan náà ni wọ́n tún ń pè ní orí inú. Yorùba a máa sọ pé "kórí inú ẹni má ba tòde jẹ́" ìyẹn ni pé kí ẹlẹ́dàá ẹni má se gbàbọ̀dè nítorí orí inú yìí ni àyànmọ tí ènìyàn wáyé wá músẹ. Saheed Ọ̀sùpáfi ìdí èyí múlẹ̀ nínú orin rẹ nígbà tí ó ń kín ohun tí Àjùwọ̀n sọ nínú isẹ́ Oyelade sọ pé àwọn Yorùbá ní ìgbàgbọ́ pé sábàbí ló máa ń fa gbogbo ohun tó ń sẹlẹ̀ láyé .Ohun tí Àjùwọ̀n ń sọ ni pé ohun kan kìí dédé sẹlẹ́ sénìyàn, ìpín ténìyàn bá ti yàn látọ̀run wá ni. Ó ní gbogbo àwọn ohun tó se pàtàkì tó ń sẹlẹ̀ sẹ́dàá láyé ló ti yàn látọ̀run wá léyìí tó ń ṣàfihàn ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò báyé ti rí.Oyelade (1993:99)

Ọ̀ṣùpá kọrin náà báyìí:

Egbe: Ǹbá tètè mọ̀ pórí ni
Ǹbá ti má saàgùn
Mi ò mọ̀ pórí lowó, mí ò mọ̀ pórí lọlá
Ǹbá máá saàgùn

Lile: Oògùn ló lọjọ́ kan ìpọ́njú
Orí ló lọjọ́ gbogbo
Orí pípé tẹ́dàá bá kójọ, tẹ́dàá bá wọn se
Tẹ́dàá bá mọ ìgbà tỌ́lọ́run máa gbádùráà
Kò ní ṣiṣẹ́ kan débi tí yóò se wàhálà
Á máa dúró dìgbà tí nǹkan bá máa wàpa ni

Ohun tí Saheed Ọ̀ṣùpá ń sọ nínú orin yìí ni pé orí ló lọjọ́ gbogbo. Orí la fi í mẹ́ran láwo àti pé àyànmọ́ tóníkálukú ti yàn látọ̀dọ̀ aṣẹ̀dá kó tó wá ilé ayé náà ló dé ilé wá músẹ.Nítorí náà, kẹ́dàá má kánjú ju Olódùmarè lọ nítorí àsìkò ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ lènìyàn kọ̀ọ̀kan yàn láti làlùyọ láyé.

Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Ẽ̀rò Yorùbá Nípa Àtunbọ̀tán Ilé Ayé Àti Ikú

Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èròYorùbá nípa àtubọ̀tán ilé ayé ni pé ọjà ni ilé ayé. Àwọn ẹ̀dá wá sí ilé ayé wá nájà ni. Ọjà jẹ́ ibi tí a sètò fún títà àti rírà onírúurú nńkan tí ó lè mú ẹ̀dá gbé ìgbé ayé ìrọ̀rùn. Oríṣii àwọn mẹta ló sì ń wá sí ọjà: (i) Àwọn tó wá ta ọjà (ii) Àwọn tó wá ra ọjà (iii) Àwọn tó wáwòran. Àkókò tàbí àsìkò tí àwọn tó ń wá sí ọjà máa ń padà yàtọ̀ sí ara wọn. Àwọn tó lọ sí ọjà tó padà kíá ni Yorùbá máa ń pè ní àbíkú. Àwọn tó bá sì kú nígbà tí wọn wà ní ọ̀dọ́ ni wọ́n máa ń sọ pé ó kúrò lọ́jà ní ọ̀san gangan. Nígbà yẹn ni àwọn elédè Gẹ̀ẹ́sì yóò wí pé “sunset at noon” èyí tó túmọ̀ sí pé ọ̀san ni ìràwọ̀ irú ẹni bẹ́ẹ̀ wọ̀.Àwọn tó bá ná ọjà dalẹ́ ni àwọn tó dàgbà tàbí darúgbó kí wọ́n tó dágbére fáyé. Ẹni wá tajà ni Yorùbá gbà pé ó se làálàá kó tó ríjájẹ, ẹni tó wá rajà ló ráyé wa, tí ohun gbogbo tù lára àmọ́ ẹni tó wá wòran ni kò ráyé wá; ó kàn wulẹ̀ sìn wón wáyé ni.

Dájúdájú a ó kùú, a ó fi ayé òsì yìí sílẹ̀. Ìbáà jẹ́ ọba, ìjòyè tàbí mẹ̀kúnnù, kò sí ẹni tí kò ní kú. Àwọn Yorúbá ní ìgbàgbọ pébí a bá kú ní ayé, a ó tún lọ sí ayé mìíràn. Dáramọ́la àti Jéjé (1995: 150) sọ pé Yorùbá ní ìgbàgbọ́ pé bí ènìyàn bá kú,yóò tún bẹ̀rẹ̀ ayé tuntun mìíràn nítorí náà ni wọ́n se máa ń sọ pé ayé lọjà, awá nájà láyé ni. Ọ̀ṣùpá náà fìdí èyí múlẹ̀ nínú àwo orin ẹ̀re “Barrybration’:

Ẹ̀ bá rántí pé a wáyé láti wá nájà láyé
Awá nájà láyé, kána, ká dẹ̀ padà
Awá nájà nílé ayé o
Ọjà wàràwàrà má jẹ n bá wọn na
Ẹlòmíì wáyé, á na láfẹ̀mọ́jú
Ẹlòmíì wáyé, á na lọ́sàn án gangan
Ẹ̀ bá rántí pé a wáyé láti wá nájà láyé

Bójólówó ni, o wáyé láti wá nájà ni

Tálíkà gan wáyé ni láti nájà láyé

Awá nájà ni láyé

Kána ká dẹ̀ padà

Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá nípa àṣẹ̀yìnwáyé ló máa ń jẹ́ kí wọ́n nígbàgbọ́ pé arúgbó tó bá kú yóò tún padà wá nípasẹ̀ yíyà lọ́dọ̀ ọ̀kan nínú àwọn ọmọ rẹ̀.Dáramọ́lá àti Jéjé (1995: 161). Èyí jẹyọ nínú orin fújì yìí níbi tí Ọ̀ṣùpá ti kọ́ lórin pé:

À ní ẹsẹ gìrì ayé lọ sọ́run bọ̀ màa ló ń wá sáyé

Bẹ́dàá se ń lọ sọ́run bọ̀, màà ló ń wá sáyé

Bóyá nínú ẹni tó ń lọ ni woṇ́ ti rò pé ó ń darí

Bí wọ́n bá bí ọkùnrin padà, wọ́n a ní Babátúndé

À ní nínú ẹni tó lọni wọ́n ti rò pé ó ń darí

Bí wọ́n bá bí obìnrin, wọ́n a ní Yétúndé

Òun ni wọ́n fi ní ayé ẹni tó ti kú nìkan ló parẹ́

Ìran kan lọ, ìkan ń bọ̀

Wọ́n á tún wá sáyé

Ó tẹnumọ́ pé ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé tí ènìyàn kan bá kú, tí wọ́n bá bí ọmọ lẹ́yìn ikú rẹ̀, wọn yóò sọ pé ẹni náà ló tún ayé wá. Òun ló fà á tí wọ́n fi ń sọmọ ní Babátúndé àti Yétúndé.

Àwọn Yorùbá màa ń sọ pé ilé ayé ilé asán, nítorí ohun gbogbo tẹ́dàá bá mú wá ayé náà ni yóò fi sílẹ̀ lọ́jọ́ tí ikú bá dé. Ìgbaniníyànjú àwọn Yorùbá ni pé ẹ̀sọ̀ pẹ̀lẹ́ layé gbà. Olórin yìí náà kín èrò àwọn Yorùbá lẹ́yìn nígbà tí ó kọrin pẹ:

Ẹ̀dá ò mọ̀ pé afẹ́ ayékan

Gbogbo kómídè kómí ogun bó tilẹ̀ wù kó jẹ́

Lọ́jọ́ kọ́jọ́ táyé bá pin mà lótán

Ìyẹn máa dìtàn sí ilé ayé níkọ̀ọ̀kan ọ̀run

Bí ò ń sáré owó, ṣèrántí ọ̀run

Bí ò ń sáré ilé, ṣèrántí ọ̀run

Ọkọrin ló ń fi orin yìí ṣàfihàn pé ilé ayé, ilé asán ni. Kò ṣe é wà máyà nítorí ọjọ́ tẹ́dàá bá ti kú ni gbogbo rẹ̀ tán. Ikú lágbára lórí gbogbo ẹ̀dá nítorí kì í gbowó tàbí obì, bẹ́ẹ̀ni kò sì gbẹ́bẹ̀ nítorí náà ló fi yẹ kẹ́dàá máa se jẹ́jẹ́.

Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Èrò Yorùba ́Nípa Olódùmarè

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè ni Ọlọ́run, adẹ́dàá, aṣẹ̀dá ẹni tí ó dá gbogbo ilé ayé. Ìdòwú (1962:39) sọ pé àwọn Yorùbá nígbàgbọ́ nìnú Olódùmarè:

> The Yoruba do little abstract thinking. Their picture of Olodumare is, therefore, of a personage, venerable and majestic, aged but not ageing, with a greyness which commands awe and reverence. He speaks; He

commands; He acts; He rules; He judges; He does all that a person of the highest authority, in whose control everything is, will do.

Àwọn Yorùbá màa ń ro àwọn èrò kan tó lágbára. Àwòrán Olódùmarè tí wọ́n ní ni: Ọlọ́lá, Olówó, Agbómátìí, Arúgbó ọjọ́, tí gbogbo èniyàn ń wárí fún. Ó ń sọ̀rọ̀; Ó ń pàṣẹ; Ó ń darí; Ó ń dájọ́;; Ó ń ṣe ohun gbogbo tí ẹni tí ó bá wà nípò àṣẹ le è ṣe.

Oríṣiriṣíi orúkọ ni àwọn Yorúba máa ń pe Olódùmarè gẹ́gẹ́ bí àkọọ́lè Ìdòwú (1962:39-47). Àwọn orúkọ yìí náà ni Saheed Òṣùpá se àkójọpọ̀ rẹ̀ láti fi ki Olódùmarè nínú orin. Èyí ló ń fi títóbi Ọlọ́run hàn gẹ́gẹ́ bí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá ti ṣàfihàn rẹ̀. Ó ní:

Ta ni kò mọ̀ pé Ọlọ́run ni, kì í se èèyàn kó lọ sọ

Saridon papa di olórin àgbáyé

Ọlọ́run, ọ̀rọ̀ rẹ gàgàrà, ọ̀rọ̀ rẹ dàbí nǹkan

Aláṣẹ láyé, Aláṣẹ láyé, kò sóhun kankan tí ìí rí

Aláṣe láyé, Aláṣẹ lọ́run, òun gangan lọba ògo

. . . .

Tí kò bá wu Ọlọ́run se, ta ló fẹ́ yẹ ọwọ́ ẹ̀ wò

Ó tóbi lọ́ba, ọ̀rọ̀ rẹ̀ dàbi nǹkan

Alèwílèse bí ó wù ú se

. . . .

Ohun tó fidá ayé, ẹ gbọ́ ná, ta lólè yé?

Ohun tí ó fi dá ọ̀run, Òun nìkan lólè sọ

Ọkọrin ló fi ìmọ̀rírì ìgbàgbọ́ Yorùbá nínú Olódùmarè hàn gẹ́gẹ́ bíi Adẹ́dàá, Aṣèdá, ẹni tí kò se é yẹ̀ lọ́wọ́ wò tàbí béèrè ìbéèrè lórí ohun kan. Òye rẹ̀ kọjá òye èda.Ìdòwú (1962:49) fìdí gbogbo àyọlò yìí múlẹ̀ nígbà tí ó sọ pé àwọn Yorùbá ní ìdánilójú pé gbogbo ayé àti ohun tí ó wà nínú ayé ló jẹ́ tiOlódùmarè.Ọ̀kọrin ló ka Olódùmarè sí alátìlẹyìn rẹ̀, tó sì fi ìmọ̀rírì hàn pé láìsepé Ọlọ́run lọ́wọ́ sí ọ̀rọ̀ òun, òun kò bá má ti di ìlúmọ̀ká olórin káàkiri àgbáyé.

Lákòótán, Òṣùpá ló tún ṣàfihàn ìfẹ́ tó ní sí àṣà Yorùbá nígbà tó ń bẹnu àtẹ́ lu bí wọ́n se máa ń sọ pé kí wọ́n yé sọ èdè Yorùbá láwọn ilé ìwé wa. Ó ní :

Yorùbá dùn ún kọ́

Yorùbá dùn ún kà

À lọ́gbọ́n ń bẹ lédè Yorùbá, ẹ kọ́gbọ́n

Ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá wa, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ la fi tu

Yorùbá, ẹ kọ́ ọmọ yin

Kó lè kọ, kó tún lè kà èdè abínibí

Lára àṣàYorùbá tí ó ṣàfihàn Saheed Òṣùpá bí onímọ̀ nípa ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò àti àṣà Yorùbá ni ó tún farahàn nínú orin tó kọ nípa ìtumọ̀ òwe Yorùbá nínú àwo "Transparency." Ó gbé èdè Yorùbá lárugẹ nígbà tí ó ń kọrin báyìí pé:

Tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ tán bá ń pòwe nílẹ̀ Yorùbá
N ò tètè mọ̀, é, mo gbọ́ pé ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ ni wọ́n ń tú
. . . .
Wọ́n a ní bọ́mọdé róyin a sàkàrà nù,
bó rálágùntàn tó ń tẹ̀lé o, tó bá rẹ́lẹ́sin, á dẹ̀yìn bọ̀
Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ ni wọ́n ń tú
. . . .
Wọ́n á ní bó kọjú sími, á kẹ̀yìn sí wọ kángun
Òun lọ̀rọ̀ tí ń bẹ nílẹ̀ yìí
Ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ yìí ni pé ìrònú kálukú wa sọ̀tọ̀tọ̀ o
Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ la fi tu

Ọ̀ṣùpá ló fihàn pé ògidì ọmọ ilẹ̀ Yorùbá lòun. Ó bẹnu àtẹ́ lu bi àwọn Òyìnbó ti fẹ́ fi èdè àti àṣà wọn bo ti Yorùbá mọ́lẹ̀. Ó wá gba àwa ọmọ Yorùbá níyànjú láti máa gbé èdè àti àṣà wa lárugẹ nígbà tí ó fi orin yìí gbè é :

Se bí wọ́n ri pé ìṣe àtàṣà wa tó fi dérí èdè wa
Wọ́n ri pó rẹwà gidi, wọ́n gbédè àtàṣà ti wọn wa
Wọ́n fẹ́ fi mérí àṣà wa.
. . . .
Wọ́n ní ẹ má sọ vernacular níbi tán bí wa
À fi vocabulary yìí sá,
ká tó wí, kẹ́ ẹ tó máa fọ̀ yun un
Ẹ dákun, ẹ má fi pèdè wa
Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ la fi tu
. . . .
Yorùbá dùn ún kọ. Yorùbá dùn ún kà
Yorùbá, ẹ kọ́mọ yin
Kó lè kọ, kó tún lè ka èdè abínibí.

Àgbálọgbábọ̀

Láìṣi àníàní, ògúnná gbòǹgbò tí ń dátọ́ lẹ́nu ìgbín ni Saheed Oṣupa, bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa àmúlò àṣà àti ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá nínú orin fújì. Ó ṣàfihàn pé ìran Yorùbá kò kóyán àṣà rẹ̀ kéré rárá, ìdí èyí ló fi ṣàmúlò rẹ̀ nínú àgbékalẹ̀ orin rẹ̀. Ẹ̀rí láti inú àwọn àyọlò orin rẹ̀ fi hàn pé ọ̀rọ̀ ìwà ọmọlúàbí jẹ ọ̀kọrin lógún púpọ̀ bákan náà sì ni ó gbóṣùbà fún Olódùmarè gẹ́gẹ́ bi aṣẹ̀dá, ọba tó mọ ohun gbogbo. Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa orí pé orí là bá bọ, ká fi òrìṣa sílẹ̀ tún jẹyọ. Ọ̀kọrin ní ohun tí ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan ti yàn látòde ọ̀run wá ni ó wá ilé ayé wá musẹ́. Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá kò pin nítorí náà ni a fi ń pàrọwà sáwọn olórin yòókù láti máa gbé àṣà wa lárugẹ.

ÀKÓJỌ ORÚKỌ ÌWÉ

Adagbada, O (2014) Sociological analysis of money rituals as a recurrent theme in Yoruba films. *Journal of New Media and Mass Communication,* Vol. 32. 2224–3275

Adegbite, A. (1989) The influence of Islam on Yoruba music. *Orita,* 21/1:32–43.

Adeyemi, L. (2006) *Tíọ́rì Lítíréṣọ̀ ní Èdè Yorùbá.* Ijebu Ode: Shebiotimo Press.

Daramola, O. & Jeje, A. (1975) *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ibadan: Onibonoje Press.

Idowu, E.B. (1962) *Olodumare: God in Yoruba Belief*, London: Longman Group Ltd

King Saheed Osupa Life Biography (2015). http://kingsaheedosupa.blogspot.com.ng/2010/12/king-saheedosupa-biography.html.

Ladele T.A.A. et al (1986) *Àkọ́jọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Yorùbá*. Lagos: Macmillan.

Oladipo, O. (2007) The substance and significance of Yoruba philosophy. *Journal of Yoruba Studies Association of Nigeria*, 4/1: 1-13.

Olukoju, E.O. (1987). Music in religious worship. *Orita*, University of Ibadan. 118.

Olatunji, O.O. (1984) *Features of Yoruba Oral Poetry*. Ibadan, University Press Ltd.

Ogunsina, B. (2006) *Sociology of The Yoruba Novel: An Introduction.* Ilorin, Integrity Publication.

Ogunsina, B. (2006) Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá nínú orúkọ ẹran ọ̀sìn. *Ado Journal of Language and Linguistics*, 1/1:4-12.

Ogunsina, B. (2009) Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Èrò Yorùbá Nínú Ìwé Ìtàn Àròsọ Fágúnwà. Ìwé àpilẹ̀kọ tí a kà ní ìrántí D.O.Fágúnwà ní fásitì Èkó.

Omoluabi – Wikipedia. https://en.m.wikipedia.org//wiki.

Oyelade, E.O.(1993) The doctrine of predestination: A study of religio-cultural interaction. *Ife: Annals of the Institute of Cultural Studies*, Obafemi Awolowo University, Ile-Ife.

Scholes, P.A. (1952) *The Concise Oxford Dictionary of Music*. Oxford University Press.

Sunday, A.B. (2011) Verbal assault in Fuji music: The case of Sikiru Ayinde and Kollington Ayinla. *Journal of Pragmatics*. 43.1403-1421.

Musicography.

Wikipedia History of Fuji Music. https://en.m.wikipedia.org>wiki>fuji_m

Saheed Osupa The Main Man : Golden Point Music 2013.

Saheed Osupa Barrybration : The Leed Music 2011.

Saheed Osupa Transparency and Transformation: Olasco Films and Records Ltd 2015.

Saheed Osupa Kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ Ọkọ́ta: Al-Qudus Music 2015.

Saheed Osupa Like Father, Like Son: Mosebolatan Music Centre 2013.